# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 568 TUESDAY, MARCH 31, 1964 (2D)


## Rogbodiyan Şelę Bi Nwọn Ti fę Sin Oku Omidan Kan

**OPOBO:—** Ọrọ di bi o lọ ya fun mi bi awọn Ọlọpa ti yọ si awọn ti ngbe oku omidan kan Ọmọ ọdun mẹdogun lọ si ori tẹ oku.

Irohin fi ye wa wipe, nigbati awọn ọlọpa ti gbọ irohin iku omidan na, ni wọn ti lọ si ilu na lati şe iwadi ohun ti o pa a.

Awọn ọlọpa ti gbọ irohin kan pe idi iku omidan na ni wipe ẹnikan lọ lu u ti o si şe arẹ fun ọjọ mẹta ki o to ku.

A gbọ wipe bi awọn ọlọpa ti şe yọ si awọn ti ngbe oku omidan na lọ ni nwọn ba ju oku lulẹ ti wọn si fi ẹsẹ fẹ ẹ.

Ni awọn ọlọpa ba gbe oku na lọ si ile Iwosan.

Ohun ti nwọn şe akiyesi lara oku omidan na ni wipe, nwọn ri apa ogbẹ ni oju rẹ ati ni gbogbo ara rẹ.

A gbọ wipe awọn ọlọpa ti mu ọkunrin kan si atimọle ẹniti wọn ro pe, on ni o lu omidan na ni a lu ibo mi.

# IJOBA YIO HA DA OLOYE ẸNAHORO SILẸ BI ?

IBINNI:— Ni opin ọsẹ ti o kọja yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.), ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G.) ati awọn ọmọ ẹgbẹ (M.D.F.) şe ipade alabẹşekele kan, ti awọn ọmọ ẹgbẹ mẹtẹẹta na si şe ipinnu pe, ki Apapọ Ijọba Naijiria o yọọda Oloye Anthony Enahoro kuro ninu ọgba ẹwọn ki Oloye na o si le wale wa şe işẹ ti awọn ara Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria nreti rẹ lati wa şe, nitoripe ko si igi meji ti o dabi obi ninu igbo.

Lẹhin ọpọlọpọ imọran lori bi Oloye na yio tişe pada wale lati ọgba ẹwọn, awọn olori ẹgbẹ oşelu mẹtẹta ti o wa ni Ipinlẹ tuntun na da imọran pe ki awọn tẹ waya ransẹ si Dọkita Nnamdi Azikiwe Olori Apapọ Ijọba Naijiria.

Bakanna ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ mẹtẹta na tun şe ipinnu pe, iwe lasan ko to nkan, bi awọn ba te waya na tan ki awọn wa şe ni "O ran ọmọ nişẹ faiya ti i" ki awọn tun gbe enia kan dide ni Ibinni, ki oluware osi fi ipinnu awọn han Ọlọla Azikiwe.

Ki awọn enia to pari ipade won ojọ na, nwọn wa kesi Ọlọla Azikiwe Olori Apapọ Ijọba ati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Ijọba lati lo ofin idariji awọn ẹlẹwọn ti o wa lọwọ wọn, ki nwọn da Oloye Enahoro silẹ.

Lẹhin ti nwọn pari ipade na tan, ni nwọn wa tẹ waya si Azikiwe ati Alhaji Balewa.

Şugbọn gbogbo iwonyi ko tẹ awọn enia na lọrun, nwọn tun wa da a ni aba wipe ki awọn gbe enia kan dide lati Ibinni lọ si Eko, ki o lo ri Ọlọla Azikiwe ati Alhaji Balewa lori ọrọ kanna.

Awọn enia na wa da imọran wipe. ẹniti işẹ na yẹ lati lọ si Eko ki o lọ jişẹ na fun awọn ni Ọgbẹni Ẹdọkpọlọ ti işe Olori ẹgbẹ M.D.F. ẹgbẹ oşelu ti o mba ẹgbẹ Olomi şepọ ni Ipinlẹ na.

Lẹhin ti nwọn ti yan Ọgbẹni Ẹdọkpọlọ tan, o dupẹ lọwọ gbogbo awọn aşiwaju ẹgbẹ Oşelu mẹtẹta, o si şe ileri pe on yio jẹ işẹ na gẹgẹbi nwọn ti şe ran on.

O tun şe ileri siwaju ninu ọrọ rẹ wipe on yio fi han Ọlọla Azikiwe ati Alhaji Balewa pe ẹnikan şoşo na ti awọn enia Ipinlẹ na lero pe on ni yio şe aşiwaju awọn ki awọn to gba Ipinlẹ na ni Oloye Enahoro.

Ẹdọkpọlọ tun şe alaye pe, on yio bẹbẹ ki nwọn wo ti awọn enia Ipinlẹ tuntun na ki nwọn si fi Oloye Enahoro silẹ, ki o le maa wa şe aşiwaju awọn enia Ipinlẹ Agbedemeji.

Oniwe irohin wa ni Ibinni fi ye ni irọlẹ ana wipe, ọgbẹni Ẹdọkpọlọ ti nmura lati wa si Eko, a si ro pe lọla ni ọgbẹni na yio de si Eko, şugbọn nwọn ti tẹ waya si Ọlọla Azikiwe ati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lori ọrọ na.



OLOYE ANTHONY ENAHORO
Igbakeji Baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre

### AWOLỌWỌ MBỌ?

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, ọgbẹni E. A. Mọrdi, ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ninu ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ti kesi Ọlọla Azikiwe wipe ki o lo aşẹ Ijọba ti o wa ni ikawọ rẹ ninu akọsilẹ eto ofin iselu Orilẹede Naijiria ki o yọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ kuro ni ọgba ẹwọn ki ole pada wọle lati ma a wa se olori awọn ọmọ Yoruba.

Ọgbẹni Mordi tun şe alaye wipe gbogbo awọn ohun ti o nşẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun loni ati papa julọ kakiri gbogbo Naijiria, nitoripe Oloye Awolọwọ ko si nile ni.

Ọgbẹni Mordi tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, ẹniti Ijọba fi ipa fi ori aga aye gẹgẹbi aşiwaju awọn ọmọ Yoruba ko tẹ awọn enia na lọrun, nitoripe pẹlu girimakai ati tulasi on tipatipa ni nwọn fi si aye na, ion awọn enia ko si dun si i.

Ọgbẹni Mordi ni gbogbo aiye lo ti ri nisisiyi wipe ẹnikan şoşo na ti gbogbo enia orilẹ-ede yi nfẹ, papaajulọ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Wo oju ewe kẹfa

# Oloye Iroko Di Olori Gbogbo Awon Ele'gun Ilu Eko

EKO:— Ẹnu kọ irohin inawo ti baba wa Oloye D. O. Irọko na ni ọjọ Abameta ti ṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹta ninu ọdun yi ni agbole Irọko ni nọmba 18, Beckley St. Ararọmi Odo, Eko. Bi ifini joye na ti ku ọjọ mẹta ni nwọn fi ile pọn ọti ti nwọn fi ọna ro ọka, ti nwọn nse ti nwọn nsọ. Ilu bata, Aro ati Ṣekẹrẹ gba gbogbo adugbo na ti o jẹ pe ati ẹniti nwọn fi iwe pe, awọn ti nwọn pe ni ohun ẹnu, paapa alarekọja ajẹti ati amuti ni nwọn fi ẹnjẹ ati ọti Beer, Brandi, Sinapu, Ginni, Statu awọn ọti aladun ṣe ni ọjọ na.

Oloye D. O. Irọko ni o ti jẹ oye olori awọn oniṣegun ati adahunṣẹ to wa ni gbogbo Mushin ati agbegbe rẹ oruko oye na ni Alapinni. Nigbati oloye Ojebode Gbamgboṣe ẹniti gbogbo aiye mọ oruko rẹ bi Ajolojo fi ile ṣaso bora, ni awọn ẹgbẹ ọmọ Elegungun Improvement Union ba fikuluku ni nwọn gba ohun-ṣọkan pe Oloye D. O Irọko ni oye na tọ si.

Bi o ti ku ọla ti nwọn yio jẹ oye awọn enia ti nrode la ti igun mẹrẹrin Naijiria papa Oloye Iyaafin Adukẹ Obijiku iya ẹgbẹ Eleweọmẹ ti Mushin ati oloye Iyaafin Kikẹlọmọ ile Aro Uton iya ẹgbẹ elewe ọmọ Mushin ti de si ọdọ oloye na ti nwọn si nnawo na ara.

Bi o ti ku wakati meji ti ayẹye ifinijoye yio bẹrẹ ni awọn ẹ'i, ọrẹ, ojulumọ iye kan, ọgba ati ẹgbẹ oloye na ti bẹrẹ ariya ti wọn, ti gbogbo rẹ n d u n yungba bi agbayun



OLOYE D. O. IRỌKO

Ọgbẹni Bello Owonikoko Balogun fi kọngọ rẹ dabira ni ọjọ na ti Oseni Kẹhinde si nku ṣẹkẹrẹ si awọn onidi nlala nidi, ijo kini nwọn ko jo tan, nwọn jo ti Egungun Oro, Oya, Ṣango ati bẹbẹ lọ lẹhin eleyi na ni n w ọ n wa bẹrẹ ijo ti ode oni, ijo idẹra wọn jo ju kokoro lọ ni ọjọ na.

Awọn idile Irọko ti o ṣe eto ayẹye na yan awọn igbimọ Alabaṣekele nwọnṣe eto na ti Olọrun si fi yin wọn, awọn Igbimọ ni Dada Adeṣina, Alapinni, Sule Padonu, Benard I r ọ k o, F. Ogun, Babatunde Irọko Ọpayẹmi Akanbi, S. L. Ọmọtọla, Yaya Ọmọba, Bisiru Atanda ati Akanbi De lly.

IFINIJOYE

Ifinijoye bere ni deede agogo mẹfa ku ogun iṣẹju (ni irọlẹ) p e l u Iba iiju. Awọn ti o wa lati Abẹokuta ni o bere ifinijoye lo ni ki onilu koko sẹ ilu rẹ. Lẹhinna ni nwọn ni awọn ko gbe iba, ni awọn onilu ba fi ilu si pe, "Adinimọdo di gbogbo won mọle".

Nwọn tun wipe ni aiye atijọ nigbati a i y e roju nwọn jẹ iyaloje si Oke-Arin, nwọn si jẹ Oroyinyin si Oko-Awo. A tun gbọ wipe, nigbana Oke-Arin ni arin ilu, gbogbo iyoku ko dara to Oke-Arin

A fi Oloye Irọko lo wa si inu ilẹ yi ti o jẹ igbo nla nigbana, Ọlọrun yo bukun gbogbo ẹnyin ọmọ Irọko nibiti ẹ ba wa, baba nyin ṣe iṣẹ rere silẹ, Ọlọrun yio jẹ ki ẹ le j e r e iṣẹ baba nyin. Amin

Nigbati mo di ọmọ ọdun mẹfa ni mo fi Eko silẹ, mo lọ si Abẹokuta, afi igbati Oloye Irọko pe mi wa jẹ oye. Nitorina awọn iran I r ọ k o ni o tẹ agbegbe yi do.

Lati ọjọ ti o ti daiye ẹnikan ko ka iye ọdun rẹ, ṣugbọn lati oni lọ, ao bẹrẹ si ma ka iye ọdun ti o lo lori oye pe, o di ọdun kini, keji, kẹta ati bẹẹbẹ lọ. Ọlọrun ko ni jẹki a ka ọdun arun fun ọ, amin. O pe bi ope, yio yẹ ọ kalẹ, a o mọ ọdun rẹ si owo ati si ọmọ aṣẹ.

Ni nwọn ba tun fi orin "Adinimọdo, ope ati beebẹ lọ ni ariwo ta lọ gee.

EGUNGUN EKO

Iṣọri Elegungun marun ni o wa ni ilu Eko, Irọko, Ọya, Bamgboṣe, Ope ati Ajolojo.

Ni awọn ti yio ja ewe le Oloye D. O. Irọko lori ba de arabinrin kan ru panu nla kan, egun meji tẹle e gbogbo awọn Olọjẹ Eko si tẹle Egungun na.

EWE OYE

Egungun wa kọko si oribalẹ fun Oloye na ninu ọla nla rẹ, oso ti o ṣe o kọ siso ti gbogbo awon mọlebi rọyi wọn ka, Alagba bẹrẹ ayẹ yẹ Ijawe oye lenilori pelu orin ohun gbogbo nt'ogun awa ṣe etutu ni, ohun gbogbo t'ogun. O tun juba o ni ti o ba ku alagbẹdẹ pelu omo rẹ nwọn a ma fi na fun ara wọn.

Eriwoya! Ayada, ayatọ Osoro, ao soro rere ko mọ ni ṣe o beni ko ni yẹ, ao sorọ rere o ati bẹbẹ lọ. Loni awa si ile baba wa Ojẹniran lati wa fi wọnjoye to si sile.

Nwọn ki ọpọlọpọ ifa ati awọn ijinlẹ ede Yoruba ki nwọn to bẹrẹ aṣeyẹ na. Olori awọn Elegungun gba panu ti nwọn gbe wa, o si gbe lọwọ, o bere ẹniti yio

Wo ọju ewe Karun

## Akọwe Olowo—Ori Kan Fara han Adajọ Kọtu

IJẸBU-ODE

Akọwe Agbowo-Ori kan ti nṣiṣẹ fun Ijọba Ijebu-Ode Ọgbẹni Baṣiru Saaka ni irohin fi ye wa pe ofi ara han ni kọtu adajọ fun ẹsun ole jija.

Irohin na fi ye wa pe awọn Ọlọpa fi ẹsun kan pe Saaka ti owo ti oju ọọọjọ ponun lọ (£173 1s 3d) ti ṣe owo Ijọba Ibile Ijebu Ode (Ijẹbu-Ode District Council).

Ẹleri Ijọba kan Ọgbẹni Dauda Akewuṣọla ti iṣe Ọga awọn olowo ori ni ilu Ijẹbu Ode sọ fun ile ẹjọ pe l ẹ h i n igbati Saaka gba awọn owo wọn yi jọ ni ilu Ilese ati Ewuwọn ni oba naa.

On fi kun pe, nigbati awọn se eto ati le gba owo na lọwọ Saaka ni ọrọ ba di aki ti yan.

Saaka ti fi han ile ẹjọ na pe, on ko jẹbi. Adajọ kotu na si un gbigbọ ẹjọ na siwaju

# Ẹgbẹ Ọrẹ Mẹta Ṣe Ajọdun

EKO:- Irohin ko to afojuba ni ipade ti ajọdun nla kaa ti awọn ọmọ ẹgbẹ Ọre mẹta ṣe ni Nọmba 3 Apatẹ-Mọta Street, Eko ni ọjọ Aiku tiṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu keji ninu ọdun yi bi o ti ku wakati meji ni awọn ero ti nde awọn ọrẹ ẹniti o wa woran ati oriṣiriṣi awọn obinrin ati Ọkunrin.

Ọgbẹni Buraimọh Ajao ile Oye ti o jẹ Onisakara lo fi orin dawa laraya ofi kọkọrọ ilu rẹ dara ni ọjọ na, Olu wabiwọsi ilu ni ọjọ na.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ẹmi wa ti o dasi di ẹjọ ori ti a nṣe ajọyọ na, inu gbogbo enia ndun sinkin, nwọn nfo soke fun ayọ.

Awọn ẹgbẹ ti o wa sibi aṣeyẹ ọjọ na ni yi, ẹgbẹ mẹfa, ẹgbẹ ọre mẹsan, ẹgbẹ ọrẹ Mẹrun, ẹgbẹ ọrẹ Mẹwa ẹgbẹ Tiwalagba ati awọn enia jankanjankan miran.

Die ti aye wa fun wa lati daruko ninu awọn enia sarakisaraki ti o wa ni ọjọ na ni wọnyi, Y. A Giwa, olori ẹgbẹ, Lawdi, Dele, Alufa Suberu, K. Atanda akọwe isan owo, K. Alabi Ẹlẹmọshẹ, Ọlọla R. A. Adio Bakare akọwe gbogbo eto ẹgbẹ.

A ṣeyi ṣamọdun o.

## IRAWỌ RẸ WO

AQUATIUS (Jan. 21 - Feb. 19) Awọn ọdọmọde yio nifẹ lati ma ba obinrin ṣe pọ loni ati lati ba obinrin se ọrẹ papo

PISCES (Feb. 20 - March 20) Ṣọ ọrọ sisọ rẹ loni, nitoripe ibere kan ti iwọ yio dahun yio jẹki iwọ paapa ri oju ilẹ de ip ti iwọ yio fi ba alagbara enia ṣọrẹ.

ARIES (Mar. 21 April 21) Ṣọra rẹ gidigidi nipa owo loni ki o si wadi enia wa daradara ki o to fi owo ba ṣerẹ.

TAURUS (April 22 - May 21) Ohun ti o dara fun ọ ni pe, ki o wa ọna ti ija ti o mbẹ nilẹ yio fi pari, ki o si mu ọkan rẹ kuro nibẹ patapata.

GEMINI (May 22-June 21) Mura si ohun ti o fẹ ṣe Ọlọrun ti lọwọ si awọn ogun Orun si ti dide lati ran ọ lọwọ.

CANCER June 22-July) Iwọ yio ṣe orire lọpọlọpọ bi o ba le ni ifọwọsowọpọ pelu ẹlomiran, nipa iṣẹ tabi nipa faaji.

LEO (July 24-Aug 23) Orire ni tire ni gbogbo ọna, iwọ o sijẹ anfani lati ọdọ ojulumọ, ṣugbọn ki o itọju owo rẹ ki nwọn ma ba gbọn ọ do

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Gbogbo laalaa ati a apọn ti o ṣe nipa iṣẹ rẹ, omulẹmofo ni yio jasi, ayafi ki o tun ero na gba

(LIBRA Sept. 24-Oct. 23) Tọju owo rẹ ki o maṣe na inakuna nọwọ rẹ si ohun ti o ri pe o dara.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 23) Tun iwa rẹ yio pada si awọn ẹbi rẹ nitori pe akoko mbọ ti iwọ lo ọgbọn ori sipa tiwọn

SAGITTAIUS (Nov. 24 Dec 23) Ore ti iwọ yio ba ọkunrin ala gba ranṣẹ yio ṣe ọ ni anfani daradara nibiti iwọ ko nireti rara.

CAPRICORN (Dec. 24-Jan. 20) Edraiyede yobẹ ṣilẹ larin iwọ ati ọkan ninu ẹbi rẹ suru ni ẹbọ.

## Ema Ka Iwe Irohin Imọlẹ lojojumọ

BERE OJULOWO EGBOGI:—

# Congreve's Femae Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu lara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba

Igba — aiya riru ọmu riro, didun are atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gegebi Ajo fun ilera ati oriṣiriṣi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:—

# mmoniated Quinine Tincture

Nigba laila ki awọn Oriṣiriṣi rọbirọki egbogi ti wọn nko wa nisisiyi to de awọn ag alagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu kọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti aiperi nyọ ienia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ila-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbog aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati oriṣiriṣi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Ponech Nigeria, (Ọja Ita Faj)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GEGẸBI a ti fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, awọn ti tu ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ ni torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ ti tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun ẹnian, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma me

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo, Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ẹo ma a gbọ ni ipade.

Ni torina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi, ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgbose St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni oruko awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ola. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Timothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.

# Oloye Iroko Di Olori

Lati oju ewe keji

ba gba fun Oloye na, ni Iyaagba to joko ti Oloye na gba fun Oloye Iroko.

Lehin na ni Alagba ba tun gba pada, o si si inu re, nwon ba awon nkan ti oje etutu lati fini joye yerosun efun osun ati ewe iyeye nwon si se orona gegebi nwon ti se e

Lehin, na ni nwon gba opolopo adura fun gbogbo e n i a laiku enikan i Nwon tun gba atata adura fun Oloye Iroko nwon ni eleda re lo yan o, ko ni hun o, o ni si iwa hu, gbogbo enyin Irunmole e ma je ki nkankan o se.

Akowe awon Egbe Elegungun Eko Ogbeni S. A. Aderibigbe Giwa ka iwe ti nwon fi yan Oloye na si ipo nla. O ni ipo Olori Apidan ni awon ko ro ti awon si kowe re ranse si won, ni awon ba pe ipo yen momo kere o. Ni awon ba ko iwe nla miran si won pe, Olorun ti tun gbe nyin ga, ipo Oloye Olori gbogbo Elegungun ilu Eko ati agebgbe re ni awon fi nyin je. Ni oba yo eda iwe ti nwon ko, o si ka.

Bena ni Alaga awon Elegun Eko, Ogbeni O. Falade na tun wi bi ti akowe ni on na ba se adura fun idile Iroko, o si so pe, on fe ma ri won ninu ipade awon Elegungun

Ni Oloye na, Oloye D.O. Iroko ni inu on dun si ipo ti nwon ni o to si on yi. O ni bi nwon ta fi on je oye "akewe eko" ninu ile baba on, o to on lorun depo oye nla ti nwon gbe fun on yi.

Lagbara Olorun on yio se ti Olori awon Elegungun na yio fi ni ade bi awon Babalawo ati Onisegun tise ni, otun so pe, bi on yio ba wuye Lagbara Oluwa ade ni nwon yio ba lori on.

Ni onif to ba ya gbogbo enia ati Oloye na pelu awon emewa re.

Awon enia to wa lati Ibadan Abeokuta, Shagamu, Ijebu-Ode, Shomolu, Mushin, Oshogbo, Ede, Oyo, Ogbomosho ati bebe lo.

Die ti aye wa fun lati daruko ni ogbeni S. A Ola Lawal lati Mokoloki agbegbe Abeokuta. Musitafa Olawale lati Ijaiye Adeyemi Adesina lati Ijaiye. N M Bello lati Ibara ati Omolade Adio Ijaiye gbogbo won wa lati Abeokuta.

Ogbeni S. O. Okunromade Akowe awon Adahunse Eko Iya afin L. M. Joseph eniti oti fi gbakan je asoju ninu Ijoba Ibile Eko ri ogbeni A Babatunde Iroko ti oje igbakeji Alaga egbe Alakuko ni wodu C. 5, Eko

Ogbeni Ramonu Agunbiade lati Shomolu, Oloye Morgan Apena Agbaiye ti Eko, Oloye Oyegoke Oluwo Agbaiye ti Eko, ati Oloye Sobayo Alagba Oje Mushin, Oloye E. O. Oyegunle olori Lisa Abule Ijesha, Oloye Tiamiyu Isola Otun Lisa Abule Ijesha ati Ol o y e Fasore Balogun Lisa Abule Ijesha ati Felies Ayod e l e Iroko.

Oye yio mo ri o, Aje gbo, aje ty ase.

## Ogiri Wolu Awon Osise Eedu

ROSIA:- Oro di bi o lo ki o ya fun mi nigbati ogiri koto nla yaa lu awon osise inu koto ti nwon nwa edu iwo oko Reluwe larin ose to koja yi ti osi wo lu won mole.

Irohin fi ye wa pe, awon osise eedu yi ko tete fura si pe awon osise won kan ti ku sinu koto a fi igbati nwon reti won fun nkan ki ojo meta ti nwon ko ri ki nwon jade lati inu koto.

Irohin na fi ku pe ile se ni ko ti le so iye awon ti o ku sinu koto na.

Sugbon ise irohin kan ninu Rosia ti anpe n PRAUDA ni ose ikede iku awon osise ile ise awon omo egbe ti se Ijoba ile na (Communist Party).

Aki gbogbo awon ebi ati ara awon ti oti ku won yi, Oluwa yio te won si afefe re o. Amin.


BERE OJU OWO EGBOGI AWON FARANSE TI NWON NPE NI- Eleyi yato patapata si awon Robi-robi. Ise re lara enia si daju fun Iwosan gbogba Kokoro buburu ti o ba wa ninu, EJE ARA bi Mo mono

RICHALET

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Meji re ko si ni gbogbo awon Egbogi ti nwon npe ni TONIKI Eje ti nwon si nti kakiri ni owo popoku adimowo tabi ki o lo nile ko di o w o Iyen se ewo, awa ki ta awon egbogi ba won yen rara tab ti nwon npo ta ni ile yi.

Gegebi awon Onibara wa ti mo irufe awon egbogi ba won yen a ma a ba oju owo egbogi atata ti a ranse fun tita lati awon ilu Jamani, Faranse ati ti awon Jatambulu si Itali je.

Mo daju pe, bi eje ara ko ba mo daradara awon amodi tabi ailera wonyi le se o, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju susu tabi didun, Jedijedi Ako iba, arun Edoki, Aya - didun pupo ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ese Amodi Apo ile ito, ehin didun tabi ibaradi riro pelu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu eje ara re patapata yio si fo eje re mo tonitoni pelu.

Sa dan igo re kan wo iwo yio si ma a rohin re fun elomiran pelu.

Bere egbogi aejbina Pyal yi ni sobu wonyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba



AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Odunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Odun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgbose Street, Irohin Imole Offices Wemimo Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 568 TUESDAY MARCH 31, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lehinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe [illegible].

Eyi ki iṣe bẹ rara, asi fẹ fi yẹ gbogbo enia ki o yẹ wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣẹ fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun [illegible] (19[illegible]) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985. LAGOS

# ỌWỌ AWỌN ỌLỌPA TẸ GBỌMỌGBOMO KAN

IJẸBU-ODE:— Ọrọ kọ sisọ, ti keke si pa a mọ gbogbo awọn ero ti o pejọ si ile ẹjọ giga ti ilu Ijẹbu-Ode lẹnu larin ọsẹ ti o kọja yi, bi awọn ọlọpa ti nfi ẹsun ole kan ọdaran aboyun kan, Falilatu Kadiri ti iṣe ọmọ ogun ọdun fun ẹsun ọmọ gbigbe. Niwaju adajọ agba Ọlọla Charles Madarikan ni nwọn ti ba obinrin aboyun yi ṣe ẹjọ wipe o fi ọgbọn alumọkọrọyin ti ole ji ọmọ oṣu mẹfa Oluṣesan Adesoyi tiṣe ọmọdekunrin Ọgbẹni Zacheaus Afọlọrunṣọ ti ngbe nọmba 6, Rest House Ijẹbu-Ode ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun ti o kọja yi.

Ọkan ninu awọn ẹlẹri Ijọba ni ẹgbọn Oluṣesan ti Ọdaran yi gbe, ti a npe ni Adekunle Afọlọrunṣọ ọmọ ọdun mewa, o ṣọ ninu ọrọ rẹ pe ni ọjọ ti ọdaran yi ji aburo on gbe, Iya awọn fi aburo on silẹ pẹlu on lati dijọ ma sire ni iwaju ile, ni Iya awọn fi lọ di irun ori rẹ nitosi ile awọn.

O sọ wipe bi awọn mejeji ti sere lọwọ, ni ọdaran aboyun yi wa ti osi bere Iya awọn ti on sisọ fun wipe oti lọ di irun ori rẹ ni ọdaran na ba sọ wipe on yio joko de Iya awọn.

Lẹhin igbati Ọdaran yi joko tan ni oba ran on wipe ki on lọ ba on bu omi wa ninu ile ti on si fi aburo on silẹ ni ode pẹlu rẹ, ti ọdaran na si nba sere Adekunle tun sọ wipe ki ohun to bu omi jade ninu ile ni ọdaran yi ba ti gbe aburo on lọ lai dagbere.

Oni were ni ohun kigbe ti gbogbo aladugbo si tu jade ti wọn si ba on wa ọdaran yi pẹlu ọmọ ti o gbe salọ. Adekunle sọ wipe o to ọjọ kẹrin ki nwọn to ri ọdaran na pẹlu aburo on.

Ẹlẹri keji ni Iya ọmọ ti ọdaran yi jigbe, Iyaafin Olubọla, o sọ fun ile ẹjọ wipe bi on ti ti ibi ti on ti lọ di irun ori on de ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni on gburo pe aboyun kan ti ji ọmọ on gbe lọ.

O tun sọ wipe ọkọ on bẹrẹ si pin aworan ọmọ ti ọdaran yi jigbe lọ fun gbogbo enia ki awọn ọlọpa to ba awọn ri lẹhin ọjọ mẹrin ti o ti gbelọ.

Ṣiwaju aboyun ọdaran yi sọ fun Adajọ pe on ko jẹbi ẹsun ti nwọn fi kan on.

Adajọ wa tun sun gbigbọ ẹjọ na di ogunjọ osu kẹrin ọdun yi.

Bi nwọn ba ti se ẹjọ na si ẹo tun ma gbọ

## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!


Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbile. Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi "Linituss"

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igbẹ aiya ikọ Igbẹdu, ikọ-oṣafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pelu kelẹbẹ tabi ti o ma ojẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣọrọkiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street (Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Fali)


## Ijọba Yio Ha Da Oloye Ẹnahoro Silẹ Bi?


Lati oju ewe kini


Ọgbẹni Mordi tun fi ye awọn ọmọ Ile Igbimọ wipe, ti a ba fẹ ki ifọkanbalẹ, Ijọba ifẹ, ati alafia o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ẹniti awọn enia Ipinlẹ na ba ifẹ ni o yẹ ki Ijọba fun wọn.

O tun sọ pe, "Ẹniti awọn Ojulowo awọn ọmọ Yoruba nfẹ lọwọ bayi loni ni Oloye Awolowo.

Ọgbẹni Mordi, ni, E fi ohun ti mo nwi yi si ọwọ osi nyin, ko ni si ifarabalẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria titi ti Oloye Awolọwọ fi pade de."

Oni ohun ti awọn enia Ipinle na nfẹ ti ẹba fẹ gbọ otitọ ọrọ ki se pe ki afi tipa mu ẹnikan ti awọn enia ko fẹ ṣe olori wọn, bi Ijọba ba si fi ipa muẹn kan si ori oye fun awọn enia, eyi ko le mu alafia wa ni Ipinlẹ na.

Ni ipari ọrọ re, ọgbẹni Mordi tun sọ siwaju wipe, "niwọn igbati Oloye Awolọwọ ba si wa ni ọgba ẹwọn aifọkanbalẹ yio ma a wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun, bẹni idaamu ati wahala yio si ma a wa ni Orilẹ ede Naijiria."

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ kan fi ye Oniwe irohin wa wipe, lati ọjọ ti Ijọba ti nba Oloye Awolọwọ ṣe ẹjọ ni ko ti si iṣẹ ni ilu mọ.

O tun sọ wipe ogunlọgọ enia ni ko ni iṣẹ mọ, awọn ti nwọn ni iṣẹ lọwọ ko mọ bi nwọn ti nṣe owo ti nwọn ngba lẹnu iṣẹ wọn.

Bi nwọn ti ngba owo na oju ni nwọn fi ri i, nwọn ko mọ bi awọn ti ṣe ngna owo na ti o fi ntan.

Eyi ti owa burujulọ ni wipe, ọgọọrọ enia larin ilu, paajulọ awọn ọdọmọde ti nwọn ṣẹṣẹ jade ni ile-iwe.

Agbọrọsọ na wa pari ọrọ rẹ bayi pe "Bi obinrin ko ba dan ile ọkọ mẹji wo, ko ni mọ eyiti o san."


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) P. O. Box Bariga (31/3/64)